# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No 599 THURSDAY MAY 7, 1964 (2D)


## "IṢẸ ỌWỌ MI NI MO NJẸ"

AKURẸ:— Gbogbo enia ti o wa nile ẹjọ kekere Akurẹ ni nwọn ya ẹnu silẹ ti nwọn ko si le pade mọ nigbati Ọdaran kan, Ibrahim Zaria, ọkan ninu awọn Ọdaran marun ti awọn Ọlọpa mu wa siwaju adajọ Agba ile ẹjọ kekere fun ẹsun idaluru ati iba ohun ini ọmọ enia jẹ sọ sa o niwaju adajọ pe, "iṣẹ ọwọ mi ni mo njẹ" ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi.

Ọdaran na fi ye ile ẹjọ pe, ọọnun ma run ni Oloye Fani-Kayọde ma a nfun on ti o ba ti nlọ si idalẹ tabi irinajo kan lati tẹle lọ. Iṣẹ ti on si ni lati ma kigbe pe, "Power! Power!! Power!!!" on ko ni iṣẹ meji ti o ju eyi lọ.

Ọdaran na ni nwọn gba on lati ma kigbe ni, iṣẹ ọwọ on ni on si nṣe nigba ti Oloye Fani-Kayọde ati Oloye Akintọla lọ si Akurẹ ati Ọwọ ki rogbodiyan to bẹ silẹ ki nwọn to mu on.

Nigbati adajọ bere lọwọ Ọdaran na ohunti on fi ada olojumeji ṣe, Ọdaran ni ada olojumeji na ni on fin jẹun, egboṣi ti o wa ni ọwọ on ti awọn Ọlọpa gba ni on fi nṣe iṣọra, nitori ọjọ ti ile ba daru.

Gbogbo kotu na lo daru nigbati ọkan ninu awọn Ọdaran na ṣubululẹ nigbati o rojọ tan ti o lọ joko. Adajọ yio ṣe idajọ ni owurọ yi, bi nwọn ba ti pari rẹ si, ẹ o ma a gbọ.

## Adebiyi Sọ Pe :

# ỌREDẸHIN KO NI ẸJỌ LATI JẸ NIWAJU ADAJỌ

EKO:— Ọgbẹni Duro Adebiyi, abanirojọ pataki fun Apapọ Ijọba Naijiria sọ sako niwaju ijoko Igbimọ awọn adajọ marun ile ẹjọ gigajulọ fun orilẹ-ede yi ni owurọ ana pe Ọgbẹni S. T. Ọrẹdẹhin ati Ọgbẹni J. O. Lawson ti adajọ Ṣowẹmimọ ṣe idajọ ẹwọn fun, ko ni ẹṣẹ lọrun ko si si ẹjọ ti o kan wọn ninu ọran ti o delẹ yi.



Ọgbẹni 'Duro Adebiyi
Agbẹjọro Ijọba

Nigbati adajọ Agba fun orilẹ ede Naijiria, Ọlọla Adetokunbọ Ademọla nbere lọwọ abanirojọ pataki fun Ijọba lana, o gba wipe awọn enia mejeeji na ko ni ẹṣẹ kankan lọrun, ko si si ohun ti o kan wọn ninu ẹjọ iditẹ si Ijọba.

Siwaju eyi ni Ọgbẹni Duro Adebiyi ti sọ fun ile ẹjọ pe, ọtọ ni ẹjọ ti Dokita Oladipọ sọ niwaju adajọ ọtọ si ni eto ti Oloye Awolọwọ Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre nṣe la bẹlẹ.

Ọgbẹni Adebiyi wa ṣe alaye pe, ẹjọ ti Alhaji Ibrahim Immam ro niwaju adajọ eyi ti o wa ni oju ewe ẹrindinladọfa (page 106) fi ọrọ yi han gbangba iru eto ti awọn mejeji fẹ ṣe ni ọjọ na.

Ninu iwe na, Alhaji Imamu sọ bayi pe, "Iwọ (Awolọwọ) ati Dokita Maja jijọ pade, ẹ si sọrọ ṣugbọn nko mọ ohun ti ẹ sọ" Mbanefo, olori awọn adajọ Ipinlẹ Ila Orun Naijiria wa bere lọwọ ọgbẹni Adebiyi

Mbanefo: Njẹ o le ṣe alaye lori ọrọ ti o wa ni isalẹ pe, "nwọn gba ẹru na silẹ?"

Adebiyi: "O ṣe ni lanu pe, kosi akọsilẹ fun ibere nyin, ṣugbọn mo mọ daju pe, Oladipọ Maja ati Dokita Nkrumah Alakoso Ijọba Ghana wa ninu ọrẹ imulẹ ni asiko yi"

Lẹhin eyi ni o wa pe akiyesi awọn adajọ si ọrọ ti



Dokita Maja



Oloye Awolọwọ

oloye Awolọwọ sọ eyi ti o wa ni oju ewe iwe keje (page 7) nibiti o ti sọ pe otitọ ni ọrọ ti Dokita Maja wa ba on sọ, ati bi oloye Awolọwọ ti ṣe sọ ọrọ imọran na ti Dokita Maja ngba fun baba rẹ

Nitorina mo fẹ ki ẹ mọ wipe, ọna meji ni ẹjọ yi pin si, ọna kini ni ti Dọkita Oladipọ Maja, ọna keji si ni ti Oloye Awolọwọ.

O tun ṣe alaye pe, Oloye Awolọwọ fun Dọkita Maja ni owo lati lọ ra awọn ukan ija ni Ghana.

Lẹhin ọpọlọpọ Alaye ni Ọgbẹni Adebiyi to wa fi abọ si ori ẹri ti Dọkita Sanya Onabamiro wa jẹ niwaju Adajọ

O ṣe alaye pe ki awọn adajọ wo iwe kẹfa (volume 6 page 7) nibiti nwọn ti sọ wipe, nwọn fun Dokita Maja ni ẹgbẹrun ọọnun (£1,000) pe ki o fun Ọgbẹni S. G. Ikoku ni Ghana, eyi ti nwọn fi ran Ọgbẹni Bisi Onabanjọ, eniti adajọ ti da lare ninu ẹsun yi.

Mbanefo: "Ṣugbọn nwo oju ewe karundinladọrin (page 65) nibiti Dokita Maja ti sọ pe, on yio ṣe eto lati gba owo na ni Ghana.

Adebiyi: "Bẹni, mo ri Oluwa mi, ṣugbọn lẹhin igbati o ti gba owo na tan ko lọ sọ iyẹn."

Mbanefo: "Tun lọ wo oju ewe kẹrinleladọta (page 54)"

Adebiyi: Bẹni, Oluwa mi, otitọ ni ọrọ na owo ti o wa lọwọ Oloye Enahoro ni nwọn gba pada nigbati Ijọba fi ofin pajawiri gbe. On ni nwọn ti ṣe eto silẹ fun pe, ki o wa lọ si Ghana lati ma a lọ polowo ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣugbọn nigbati nwọn fi ofin pajawiri gbe ko le lọ mọ, ni nwọn ba fi ran Ọgbẹni Ikoku lọ.

Adajọ Agba Ọlẹla Taylor: "Ọrọ ti o sọ yi ki iṣe bẹ rara."

Adebiyi: Oluwa mi, ẹ lọ wo oju ewe kọkandinlogoji ti ṣe alaye pe, ọkẹ mẹdogun ọọnun (£300,000) lati ma a fi polowo ẹgbẹ wọn."

Mbanefo: "Ṣe o nsọ nisisiyi pe, owo ti nwọn fi ranṣẹ si Ghana owo lati ma a polowo ẹgbẹ ni tabi lati fi ra awọn nkan ija ogun?"

Adebiyi: "Ninu ile



G. S. Sowẹmimọ

Oloye Awolọwọ ni nwọn ti ṣe iwe owo na ṣugbọn Dokita Maja sọ pe, Awolọwọ nwọn

Wo Oju Ewe Kẹfa



Dokita Nkrumah
Alakoso Ijọba Ghana


## Njẹ Oke—Iṣoro wa fun Ẹ Bi ?

FUN IWADI OHUNKOHUN KOWE SI WOLI

D. Abiọdun,
P. O. Box 1554,
Lagos, Nigeria.

Jọwọ fi Stampu tọrọ ati address rẹ ranṣẹ si wa lati tete da esi pada ni kiakia.

# Aṣẹ Onikumọ Ko Dara

LATI ỌWỌ HADJI AWAIYI-WAṢERE

Olukọ ire ati awọn o bi ire, a maa kọ awọn ọmọde ni ọna iwa irẹlẹ Nwọn a si maa kọ wọn ni ọna lilo ahọn,

Nwọn o fi ye wọn pe, ahọn eni bii ma ko ire ba eni. Ahọn eni nii ma tani loṣi Awọn ọmọ ire, a ni awọn ọmọ oloriire ati oninure yio tele ilana ti awọn olukọ ati awọn obi wọn ba fi lelẹ

Nwọn yio gbọ, nwọn yio si gba ekọ ti nwọn ba kọ wọn Nwọn yio si gbọn yekeyeke pelu atilehin Ọlọrun

Nwọn yio mọ bi nwọn ti ṣe nba awọn ọmọde ati awọn ọmọde ati awọn egbẹ won sọrọ pelu ahọn tutu.

Nwọn yio si mọ bi nwọn ti ṣe mba awọn ijoye, awọn oloye ati awọn miran ti o ju won lo sọ ọ pelu iteriba. Igbesi aiye won o sidun ju oyin lọ.

Awọn ọmọ buburu ko ni gbọ, ko ni gba ẹkọ ire.

Nwọn yio si ni igberaga Nwọn yio maa sọ isokuso

bi eja Bi won ba si dagba ti nwọn wa ni aiye aṣiwaju (mogaji) ile nwọn yio ma pitan ipakupa, awọn yio ma a pitan ipakupa, nwọn yio si ma a sọ isokuso, nwọn yio ma a purọ nlanla. Nwọn yio si ma a paṣẹ onikumọ.

Gbogbo awọn ọmọ lẹhin rẹ ko ni yio gba Irufẹ aṣẹ na Aṣẹ na aschi n b ọ, nwọn yio ma a da ile ru. Nwọn ko si ni ni iyi. Ẹnu opurọ ki i ṣe ẹjẹ. Opurọ ki i si gba iyi.

Ẹnyin ọmọde, ẹ gbọ ẹkọ ti awọn obi ati awọn olukọ nyin ba fun nyin, ki ẹ si gba ẹkọ na, ki ẹ ba le jere aiye ati ere ọrun. Ẹ ma ṣe gbọ awọn obi ati awọn olukọ nyin lẹnu.

Ẹnyin agba, ẹ maṣe pa aṣẹ onikumọ, ki abuku ba ma kari nyin, ki ẹ me ba ri abuku lati ọdọ ọmọde. Iwa rere dara ju wura ati fadaka lọ.

Aṣẹ onikumọ ko dara rara. Ẹni ti o ba sọ ọrọ ire si agba tabi si ọmọde, yio gbọ ọrọ ire agba ti o ba sọrọ buburu si ọmọde, yio gbọ esi buburu.

# ✶ YẸ IRAWỌ RẸ WO ✶

AGUARIUS (Jan 20-Feb 18) Gbogbo ohun ti o ba dawọle fun tita ni iwọ yio ma ri ere nibẹ Bo ba je ti ọrọ owo ni lọ sowọpọ pelu ọrẹ rẹ kan.

PISCES (Feb,19-Mar 20) Ara rẹ yio ma gbọn loni, ṣugbọn ma ṣiṣe pupọ loni, Ẹgbẹ awo yio gbe ọ loni lọ ri awọn ọrẹ rẹ, ọrọ awo wa.

ARIES (Mar 21-April 19) Iwọ yio ri owo diẹ lo loni ṣugbọn maṣe sọrọ ija bẹni ki o maṣe sọrọ to le Iwọ yio ri iṣẹ ṣe eju ara rẹ

TAURUS (April 20-May 20) Nṣe ni ki o pari ija to wa nilẹ ki o to ma ba ọrọ miran niso Awọn enia tọ mọ iṣẹ ni ṣiṣe ni ki o wa sibi iṣẹ rẹ ki o si ma ran wọn lọwọ pelu

GEMINI (May 21-June 21) Ṣọrọ ki o ma ṣe da ijọgbọn silẹ loni nipa ṣiṣe ẹgberun nkan lekan Ti iregbe silẹ Ọrọ ni yio sọ ara rẹ jade nigbati akoko ba to

CANCER (Jun 22-July 22) Orire wa pelu rẹ loni nile, loko ati nibi gbogbo ni iwọ yio ma ba ariki pade iwọ yio si ba Olorire enia kan pade loni.

LEO (July 23-Aug 22) Ọrọ kan yio ṣele to jẹ wipe nkan ti ko dun mọ ọ ni iwọ yio ba pade nibẹ, Ileri ti o se yio yio ba ire pade kọwe si awọn ojulumọ rẹ.

VIRGO (Aug 23-Sept 22) Suru ni ki o ṣe nipa ọrọ iwọ pelu ọrẹ rẹ kan inu awọn alejo ati awọn ti o ngbe ekere yi odun si ọ nigbati n ọn ba gbọ ohun ti o ṣe

LIBRA (Sept 23-Oct 23) Iree mọe fun ọ lona gbogbo, iwọ yio ma gbe tosi awọn enia rẹ, nipa bẹ ere rere yio ma sọ si ọ lọkan.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Iwọ yio ri rere gba lati ibikan wa lọdọ awọn ure lẹ Adun ni gbẹhin ijati nwọn o pari fun Ọ

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 21) Iṣaka kekere lo di nla, yi ipo rẹ pada ki o si mu awọn iṣẹ ajeji ṣe lo je faaji die pelu awọn ọrẹ rẹ ki o si sun die

CAPRICORN (Dec 22-Jan 19) Iwọ yio sak ye-i bi o ti laagu to irohin aladun kan yio Ọ lara, maṣe jẹki arẹ mu Ọ. Ara rẹ afẹ alafia ati idera pelu.

# Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun Ti Nbọ Bi ?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"
MO JẸ RI O, OLUWA MO JẸ IPE RẸ

ẹnikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe

"AFINIMONA NPA ISIN HAJI"
LỌWỌ KI OLUWARẸ MA BA SINA TABI NA OWO INAKUNA. KI O LE LO ALOBỌ MẸKKA NA DADA

t'Oluwa ọwọ ṣe Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ fun wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Olubor gbogbo ẹda patapata" Amin"

## WAS SALAM"

AKIYESI Gbogbo Musulumi Odode ni oye ki o ni Ana lọwọ nitori igbati yio ba fẹ lọ si MẸKKA

*Iye Owo 5/6, £3 fun dosini*

MANAGER
N2/99 SHITTU STREET
Ibadan


GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TONIKI

ALE-BI-ELE Egbogi Toniki wọn Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko le jeun daradara, tabi ki o male sun daa da ọrun ...n tabi lora tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara, awọn iṣe tabi wahala ṣiṣe tabi fun awọn ailera gbogbo e nyi il ọjọ ori rẹ (age) ba ti koja Ọgbọn ọdun lọ si ded'adẹrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara bọtun patabata, oju rẹ a si jolọ, sran ara rẹ ti a ti huujọ yio bẹ rẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba d'Arẹ" nigbakugba yio salọ pelu. Igbadun ati alafia yio de si ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbu:-

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Stree, Lagos.
ADEDUN CHEMISTS'
14, WAKEMAN STREET YABA.
ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:—
IṢẸ OLODUNMARE DISPENSARY OKE-BỌLA

# IWE SI OLOTU

## Ilu Esię Nfę Ile-Iwosan

Dakun gba mi laye ninu iwe rę Irohin Imolę ti aiye fęran lati ma ka ni igbagbogbo, mo si rope o lotu yio ba mi tę iwe mi yi ninu iwe Irohin Imolę fun Ijoba Ipinlę Ariwa ka ki nwon o le ma soye ileri ti nwon se fun ilu wa ni asiko ibo didi ti o ko ja yi

Nkan ti a nfę ni ilu Esię ti poju nkan ti a le mo fi ęnu wi ni okankan lo, lati iye ojo ti a ti nbę Ijoba Ipinlę Ariwa ti nwon si ko eti ikun si ębę wa.

Ilu Esię ko nfi owo-ori dida sile rara, ilu wa ko si ntapa si ofin Ijoba Ipinlę Ariwa, nitori idi eyi, a nfę ki Ijoba rere na tete ran wa lowo lati tun ilu wa şe.



AHMADU BELLO

Ninu awon nkan ti a nfę ni ile-iwosan o je itiju nla lati ri wipe ilu Esię ko ni ile-iwosan rara.

Mo bę ęnyin omo ilu Esię ma san gbagbe, ęjęki a ko iwe bere awon nkan ti a nfę ninu ilu wa.

Mo dupę aye ę gba mi olotu

Emi ni
O. Eshoun
ESIĘ

omo enia to bęręsi ma şofo nipa iwakuwa awon dęręba na

Emi ni
Sinbiatu Asakę
Itirę

## Ę Tun Oju Ona Alla Şe

Inu mi yio dun pupo bi oloru bale gba mi laye dię ninu iwe Irohin Imolę lati ba Ijoba Ipinlę Ariwa soro lori oju ona wa ti o baję ti moto ko fi leri mo rara, ti nwon nko awon oju ona na silę

Olotu odun kan ati abo ti a nbę Ijoba Ipinlę Ariwa pe, ki nwon sanu wa lati tete bawa tun ilu wa şe paapa ki nwon da oda si oju ona wa ni asiko nitoripe ni asika ojo koko a ma poju ni oju ona wa na ti awon motoonikękę ati awon ti nrinlę ma jin si koto, jinsi gęgele loju ona moto.

Airiye igba ni awon awa moto mo ko lati wa moto won wo ilu Alla nitori aidara oju ona wa na

A nbę ęnyin Ijoba Ipinlę Ariwa pe ki ę sanu wa lati tette ba wa pa oda si oju ona na ni asiko-

Olotu ęku isęajinde ara yio moję

Emi ni
R. A. Akitoye
ALLA

## Idahun Oro Celianah

Jowo, Olotu gba mi ni aye dię ninu iwe nyin ti nkowe ni ogbon ati oye ti o si nfi ona idera han wa lati fesi oro Omidan Celifanan Oręlaja ti o ojade ninu iwe nyin ti ojo kokanlegun osu kerin ninu odun yi.

Omidan Celianah Oręlaja so wipe baba kan bimo mefa, iya awon omo na si ti ku ni o ba ko awon omo na lo si idalę Ich n odun pupo nkan ko lo deede fun baba na mo, oję owo ile to po ti onile i so pe, ki ojade ninu ile fun o

Loba pe awon omo re jo, o fi oro na han awon omo rę, oluka luku si mu imoran tirę wa lorişirişi. Omiran ni ki a lo sile, omiran ni ki awon taku ati bębę lo.

Idahun temi ni wipe, orę ti omonikeji so ni o dara, oro na ni o yę ki baba na tęle omon keji ni ki awon kuku pada sile.

Mo dupę aye ti ę gba mi Olotu.

Emi ni,
A. B. Oyeyipo.
ORO

## Ko Ha si Awon Olopa Ni'lu Ni

Inu mi yio dun bi Olotu ba le gba mi laiye ninu iwe irohin rę afinimona lati kesi awon olopa amumoto pe ki nwon mojuto awon dęręba moto akero ti won nti Mushin lo si Itirę nitoripe gadigadi ni awon nha awon ero mo inu moto won, nwon ko si bikita fun ęmi omo enia.

Iba dara bi awon olopa na bale mojuto oro pataki yi ki ęmi awon

## AKIYESI PATAKI!

Eyi ni lati kede fun awon Onkawe IROHIN IMOLĘ jakejado Ilę Naijiria pe OTĘLEMUYĘ ti ti ajo de nisisiyi. Oro rę yio si ma jade ninu IROHIN IMOLĘ deede nisisiyi nitorina ki awon onkawe wa mura silę lati ma a ka igilango oro OTĘLEMUYĘ ti yio ma jade ninu Iwe wa na,

OLOTU


## Congreves Female Remedy
(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awon obinrin ti obę ni iyonu tabi amodi Inu rirun nigbakugba tabi ni ękookan ęhin-didun, ibadi-wiwo tabi sisan ęjędudu ara tabi aikoto ęję lara Inu gbigbona nigbakugba

Igba — aiya riru omu riro, didun ara atinu wa ni o ma nfa oyi - oju Ilaogun ara ęsę ara sison, ęfori tabi pęlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupo julo fun itoju gbogbo O b i n r i n gęgębi Ajo fun ilera ati orişirişi amodi miran ti o ma nyo won lęnu ni inu nigbakugba pęlu.

(OLOMI IGO NLA NI)
BERE EGBOGI ATI JO TI WON NPENI:-

## Ammoniated Quinine Tincture

Nigba lailai ki awon Orişirişi robirobi egbogi ti won ko wa nisisiyi to de awon agbalagba aiye atijo mo aju wipe kosi ohun ti a le fi Iwe egb gi yi bi otutu iko iba, orerę lukuluku onigbameji tabi a i p e r i nyo enia lęnu yala Omode tabi agbalagba ni yio şe iwosan rę bi danga ni bi oba ti ta dię sinu omi t o loworo ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itoju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfo apo-ile-ito tabi se iwosan iyonu apo-ile-ito egbogi oju didun tabi ti ona-ofun didun, ati orişirişi omiran pęlu won mbę ni şobu awon :—

Waterloo Medicine Stores,
8, PalmChurch Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Oja Ita Faji)

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba

## Iboosi Iko Ti Ojo Rę Ti Pę Lara

Pupo ninu awon egbogi robirobi ti won npolowo ti won si nta kakiri igboro ilu Eko ati ni igberiko ko ni şe iwosan won lailai afi ki ori ojulowo haunhaun atamase egbogi ti o lagbara gidigidi ti o le şe iwosan rę titi de inu ifun ati igb-aya ti yio mu o ma tu "Iko" mo bi kęlębę jade ti o ba nhu ę titi yio fi taa ni inu rę patapata. Awon iko miran wa ti o dabi ęnipe won ama la ogun tabi orişirişi egbogi tabi ti o ba ję pe bęni, agba o ni imoran wipe ki o ma lo egbogi awon ara ilu Abyssinia ti nwon npe ni "Etibard" pęlu egbogi ti o ba amu

PORAL TABLETS
THIOLYPTINE SYRUP
THYMO-EPHDRIN LINITUSS
ETIBARD ABYSSINIA POWDER

Fun iwosan iko Asima, iko fere iko otutu igba-aiya iko gbędu, iko-onafun, iko-gbigbę tabi eyiti o ma nmu ki enia ma ha ona ofun tabi pęlu kęlębę tabi ti o ma njo ki nia ru nipa wahala tabi aikoni le sun daradara losana ati loru-gbiyanju lati dan okan ninu awon egbogi alagbara gidigidi wonyi wo fun ara rę iwo yio si ri iyato gburu-gburu larin won si awon olomi şorokiti ti won nta kakiri O daju nibę iwo yio bęrę si ri alafia, iwo yio ma jęun daradara wasi ma sun fonfon pęlu Alafia de si o ni yęn

Bere egbogi ajębina yi ni şobu awon:—

Waterloo Medicine Store
8 Palmchurch Street, Lagos
Phone:-22878 ,Nigeria, (Oja ita Faji)

NIGERIA MEDICINE STORES
Tinubu Square Lagos

# Ọtẹlẹmuyẹ Nki Nyin Ọ !

Ẹ ku owurọ o, ẹnyin onkawe wa, ṣe alafia ni ẹ ji o? Alafia ni emi papa ji o, Olotu nkọ nibẹ̀u o? Awọn alabasiṣẹpọ rẹ nkọ? Gbogbo wọn ni mo ki o. Mo tile sifila mi de ibadi, mo ki Olotu pe "AGUDU MỌNI SA" gẹẹsi ni mo fọ yẹ.

Ajinde ara yio ma jẹ fun gbogbo wa o Aṣẹ. Ọrọ oni oni, dorikodo o 'd'ori awọn onimọto akero Mushin.

"Ọrọ mba ro ma ro ẹfọ" toto o ṣebi owe o. Ni ọjọ Aje ti o kọja yi ni, emi Ọtẹlẹmuyẹ gbera sọ, o di Mushin lati lọ jadi yala boya, otitọ ni, tabi irọ ni, ọrọ ti awọn kan nsọ pe, bi ẹja "SANDINNI" ni awọn onimọto na nko ero kun inu mọto lai ko bikita fun alafia ati irora awọn eni.

Irọ kan ko si ninu ọrọ ti nwọn nsọ nitori ti e be ni mo ba a.

Ki nba le tubọ to apinpin ọrọ na, mo mọọmọ ta koro wọnu mọto kan ninu awọn mọto na, bi Ọlọrun fẹ nse ni nwọn sin wa bi ẹni sin "SANSAN" Agbara kaka ni a si fi le mi, nigbati a o fi sọkalẹ ni ilu Itirẹ, ẹniti o ba lẹsẹ bo lojugun ati awọn ti nkan mi wọn bajẹ ninu mọto na ko iye.

Ṣugbọn emi Ọtẹlẹmuyẹ dupẹ lọwọ Ọ'orun pe emi mi ko bọ sinu mọto na, nitoripe ọsẹ kan gbako ni mo fi ngu imi ehin laiṣe ọmọ-agbo fun pipo ti mọto na po mi ninu.

## IBOSI OLOPA

Ọrọ yi kan Ọlọpa gbọngbọn, torina ẹ bawa mojuto. Awọn onimọto ọna Itirẹ nfẹ ibawi.

Ẹ molu ẹ! E molu ẹ!

Eyiti o tilẹ burujulọ ni ere buruku ti awọn dẹrẹba alawajamu na nfi mọto na sa loju titi koto rẹ e, awa gegele rẹ e, ti awọn awa mọto na kere lẹgilẹ ọmọ ijẹ wọn ti mọto ba nsureisakusa awọn ni nwọn ma nkigbe si dẹrẹba lete pe mo u ẹ ! molu !!

Bi awọn dẹrẹba na ba ti ngbọ bẹ ẹ, ni ori wọn tubọ ma ntaasi nwọn a si ma a fi mọto na ja ṣoorọṣo lọ bi ere laibikita fun ẹmi ọmọ enia.

## MO BA DẸRẸBA KAN SỌRỌ

Lẹnulọlọvi ni mo pe ọkan ninu dẹrẹba na ti mo si fi ọrọ wadi ọrọ lenu rẹ.

Mo bere bayi pe:

Ọtẹlẹmuyẹ: Iṣẹ ti ẹ fi nko enia si inu mọto yin bi sadinni ?

Dẹrẹba: Ọgbẹni ejọ wa kọ, ao ṣa jẹun.

Ọtẹlẹmuyẹ: Onjẹ lo ha ṣe pataki ju ẹmi ọmọ enia lọ bi ?

Dẹrẹba: Ao ṣa jẹun.

Ọtẹlẹmuyẹ: Njẹ bi ẹ ti nsare iṣakusa yen ti mọto yin ba fi bẹ ẹ jamu nkọ ? Dẹrẹba: Ọlọrun lo ni ẹmi ẹniti yio la, ko ni ṣalai ko la.

Ọtẹlẹmuyẹ: Njẹ ti ọwọ Ọlọpa ba tẹ yin nkọ ?

Dẹrẹba: Ko ju "fine" lọ Ọgbẹni.

Nigbati mo gbọ ọrọ alufansa yi tan lẹnu rẹ ni mo ba rọra ṣẹ ara mi ni ekanna mo wa sọ ninua ra mi pe, awọn dẹrẹba alawajamu yi ko kọ ki ẹmi ẹnikẹni bọ nitoripe owo ni nwọn nwa.

Laikotan, iba dara pupọ bi awọn ọlọpa ba le ṣe patama ki nwọn si gbogun ti awọn dẹrẹba na lasiko ki alafia ara ba le to gbogbo enia.

Laipẹ ejọ n-'o tun kan awọn Wolewole Mushin lara ati awọn "Landlords" ti wọn ngbẹ koto iku si arin ilu.

O di gbakanna e, ẹnyin ara mi, emi Ọtẹlẹmuyẹ, ọkunrin ti a nfi ṣepe sọ, a tun wọn ka nibiti wọn gbe idana irọ nlọ ile o Oba oke ma ṣe eyi ni animọ fun wa o Aṣẹ o.

---

**Ẹ ma a po-lowo Ọja yin Si Inu Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ**

---

## [illegible] Iyipada Ile Iṣẹ

Eyi nilati kede [illegible] awọn [illegible] wa pe ati [illegible] o ile itaja wa kuro ni Ibadan [illegible] ti wa si Ilu Itirẹ ni Agbegbe Suru Lere [illegible] Mushin.

Ẹnikẹni ti o ba fẹ bawa ra Iwe tabi Turari Ajẹbidan ki o wa si ile itaja wa ni Nọmba 1, Ishiba Street Odo Eran Itirẹ.

## Apejuwe Ile Iṣẹ Wa

Ẹ Wọ Bọọsi ti o nlọ si Lawanson ni Yaba 3d pere ni ti oba sọkalẹ ni Lawanson, bere Ilu Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ni itawe wa wa Ti o ba fẹ fi owo ranṣẹ fun ọja rẹ Adirẹsi mi niyi:-

Shoyinka
c/o Postal Agent,
Itire Via,
Suru Lere, Yaba

AWỌN IWE TI O WA FUN TITA

| | |
|---|---|
| Iwe Egbogi Awo Igba Arun | 20/- |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan . | 25/- |
| Iwe Alalati-owo Josefu Alala | 5/- |
| Itumọ Ami Ara ati Etutu | 20/- |
| Iwe Ilana Yanrin tite ati Etutu Ṣiṣe | |
| Iwe Afọṣẹ Isẹdalẹ Yoruba ati psalmu Ajẹbidan | 4/- |
| Lilo ati Agbara psalmu | 7/- |
| Turari Iṣẹgun Ajẹ ati Adura Tete damilohun | 10/6 |
| Iwe Akọmọ Lesin Islam ati Orisirisi Iwe | 1/6 |

J.O. Shoyinkan
c/o Postal Agent
Itirẹ Via Suru Lere,
Yaba.
or 1,Ishiba Street (Odo Ẹran)
ITIRẸ

---

## EGBOGI JEDIJ ED

BERE EGBOGI



## "CYCLOVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ si nyọ o lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu" tabi Iho idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Okunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni awọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn a ma pọ owo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mẹwa ninu ọgọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe bọya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara. Lẹhin ọdun diẹ iwọnu rẹ yio si tun bere bakana. Orisirisi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o bere nipa aiko ere ṣe igbọnse dede tabi lẹẹkọjumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojokanna pẹlu lojoojumọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu), pupọ ẹlomiran ewẹ nipa jijẹ Ṣuga tabi oniturari ohun adidun pupọju nigbakugba. Jẹdijẹdi orisirisi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ ade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnse, tabi ti o ba nyọ ti o ba se igbọnsẹ tan ni, tabi ti nrin ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egbogi "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa idi rẹ ki o si danwo orisi mẹta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia yio de si ekeji re ko si ninu gbogbo egbogid taa igboro ilu Naijiria jakejado Bere rẹ ni:

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Fai)

Adedun Chemist
14, Wakeman Street, Yaba

